GO PLACES
IN A
HILLMAN
FROM
ARAB BROS
MOTORS LTD.


# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.


**¡Lakaye Oro**

Jẹ Ọlọgbọn bi ejo, jẹ oniwa tutu bi adaba, kanju lati gboro, sugbọn lọra lati dahun. Ki a ku ni ẹlẹmẹsọ ki o yẹ ni, o sanju ki a di agbalagba ki a mọ ni adie rapa lọ

VOL. V No. 209 MONDAY JUNE 5 — JUNE 11 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Awon Omo Akeko binu fi Ile Eko sile nitori onje nwon ko dun

KALABA:— A GBỌ IROHIN WIPE AWỌN AKẸKỌ TI O MBE NI METHODIST BOYS HIGH SCHOOL TI ILU ORON NI AGBEGBE ILẸ KALABA, NI OLORI AWỌN OLUKỌ ILEWE NA LEJADE, TI OSI DA WỌN DURO FUN ỌSẸ KAN, NITORIPE NWỌN KUN SI ONJẸ WỌN, WIPE KO DUN. MẸJỌ NINU AWỌN ỌMỌ AKẸKỌ NA TI NWỌN JẸ OGBỌNKAN GI NI OLOTU ILE ẸKỌ NA SỌ FUN PE KI NWỌN LỌ GBELE FUN ỌSẸ MEJI LẸHIN TI A TI NA WỌN NI EGBA MẸFA-MẸFA NI DI, WỌN KO SI TUN NI GBA WỌN PADA SILE IWE YI, YIO NI BI WỌN TI MA SỌ SI.

OHUN TI NWỌN FẸ SE NIYI, LẸHIN TI ỌSẸ MEJI BA PARI, NIGBATI NWỌN BA NPADA BỌ NI ILEWE, KI NWỌN GBA IWE ERI BỌ, LATI ỌDỌ AWỌN OBI WỌN WIPE, NWỌN KO TUN NI HU IRU IWA BẸ MỌ.

Nigbati awọn ọmọ Akẹkọ nwọnyi sọ gbangba wipe, ọjọ pẹ ti nwọn ti njẹ ọbẹ ti ko dun, nwọn si kọ wipe, awọn ko ni lọ ka iwe, gbogbo nwọn si taku si ode, ni gbana ni Olukọ binu yọ ẹgba lati fi dẹru ba nwọn, ṣugbọn nṣe ni gbogbo wọn salọ, nwọn si tuka.

A gbọ wipe nibiti awọn ọmọ ile ẹkọ na ti bẹrẹ si dite yi ni, lọsọ tokọja, awọn ọmọ Akẹkọ na gbe onisẹ dide lọ ba ẹniti o kọ ile ẹkọ na wipe, gbogbo onjẹ ti nwọn nṣe fun wọn nile ẹkọ, ko dun lẹnu nwọn, ki nwọn wa ẹniti o mọ ọbẹ ṣe.

Ọgbẹni John Nufi sọ fun nwọn wipe, ọbẹ ti o ba dun owo lo pa a, On yio ṣe alikun owo ilewe wọn Nwọn fi kun owo ẹkọ wọn, ṣugbọn sibẹ ọbẹ ko dun, Awọn Akẹkọ tun ko ẹjọ wọn lọ ba Olukọ Agba, nigbẹhin nṣe ni nwọn tu awọn Akẹkọ na ka.


## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ẹe ni aṣepe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ odun sẹhin pẹlu idanlloju fun Awon iṣẹ ribi ribi ti o ti nṣe.

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to, dara fun igbona iko, otute, Aiperi, Osi inu Ọmọde, jẹdi jẹdi, kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yiu leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko se mani fun awon ọmọde. Ijafara lewu pupo, tete lọ ra tirẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

**LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*

**K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

6, Balogun Street. West Lagos Nigeria Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 24247


## Onisegun awon Soja sope, Eje ti nwon ri nigbo Elegba ko nse eje ti enia

OKE OYINGBO:- Larapa awọn enia mọkandilogun ti awọn Ọlọpa ko ninu igbo Ẹlẹgba ni Abule Ilogbo wipe nwọn ṣẹ si ofin Ijọba, ninu eyiti nwọn fi nwọn sun ẹsun wipe, nwọn ki Ọkunrin Ibo kan mọlẹ larin ode gbangba nwọn si wọ o wọnu igbo Ẹlẹgba tobẹ ti Ọkunrin ti wọn jigbe na fi nkibosi bayi pe, Ṣineke! Ṣineke!! Ṣineke!!!

Ẹniti o kọkọ wa jẹri lọjọ na jẹ ogbologbo ọjọgbọn kan lọna Oshodi (Pathologist) on lo sọ fun Adajọ wipe nigbati on lọ bẹ igbo Ẹlẹgba wo, on ri ẹjẹ lara igi ati lara igi ti o wa ninu igbo na, ibẹ ni on ti ri apa ẹjẹ. Nigbati on yẹ ẹjẹ na wo, on ri wipe ẹjẹ enia ni, ṣugbọn Ọgbẹni Adewale ti nṣe Agbẹjoro fun awọn ara Ilogbo ta ko ọrọ yẹn wipe, on ko gba wipe ẹjẹ enia ni.

Lẹhin na ni nwọn tun lọ pe Oniṣegun awọn Soja kan lati tun wa jẹri si apa ẹjẹ ti o wa ninu igbo Ẹlẹgba, ẹniti nwọn pe na ni Dokita Alexander J. Shaw, o sọ wipe nigbati on lọ sinu igbo Ẹlẹgba, on ri ẹjẹ lara igi ti o hu si ibẹ, bakanna ni on ri lara irin ti o ti kidanpapa.

Dokita na sọ wipe nigbati on se ayẹwo awọn ẹjẹ na, on ri wipe, o yatọ si ẹjẹ ti enia, boya o le jẹ ti agutan, adiẹ, ewurẹ tabi ti ẹlẹde. Ṣugbọn a gbọ wipe, Adajọ fẹ mọ Ọkunrin ti o nkigbe Ṣineke! Ṣineke!! Ṣineke!!! nigba ti awọn ọmọ Awo Ẹlẹgba ki mọlẹ loju ọna, ti nwọn si gbe wọ inu igbo lọ, o ni on fẹ ri Ọkunrin na, ki awọn Ọlọpa lọ mu wa.

Bi o ba si jẹ pe awọn Ọlọpa ko ri Ọkunrin na, on fẹ mọ nibo lo gba lọ, tabi nibo lo gbe wọle si, iru enia wo ni Ọkunrin na, nitorina ki awọn Ọlọpa lọ wa okunrin Ibo na fun ẹ., ki nwọn ṣe iwe rẹ si ode, ki nwọn sọ ninu ẹrọ Radio, ki nwọn si lẹ iwe rẹ mọ ita. Nibin ni Adajọ na yẹ ẹjọ rẹ si ighamirau ọjọ kẹfa oṣu kẹfa ọdun yi (6th June 1961).

# Ajegboro dagba Nki Nyin O!

MO KI GBOGBO Ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ kakiri Agbaiye. Mo si tun ki gbogbo ẹnyin Musulumi, ẹ ku ọdun, ẹ ku iyẹdun, aṣe yi ṣẹ amọdun, ọ p ọ l ọ p ọ ọdun Ọlọrun jẹki aṣe laiye. Amin.

Emi Ọkunrin mẹta mo tun de o! ẹ ku owurọ ẹ o jire bi? Ṣe alafia ni mo ba Nyin, ẹku ọjọ mẹta o! emi ni ọmọ Ijẹṣha lọba lọrọ mo tun de o!

### ẸNYIN ỌMỌDEBINRIN, Ẹ MURA SI ẸKỌ YIN, Ẹ MA ṢE 'KANJU JAIYE!

Ọrọ mi ti ọsẹ yi yio jẹ lori awọn ọmọdebinrin ode oni, kin to bẹrẹ ọrọ mi, mo ni lati bẹ gbogbo ẹnyin ti ọrọ mi yi ba ba wi, ki ẹ ma ṣe binu, ki si ṣe enia kan ni mo ba wi bi koṣe pe gbogbo ẹnyin ti ẹ nhu irufẹ iwa bayi lati ronu piwada ninu iwa aibikita ati aiye jijẹ. Ẹnyin ọmọdebinrin ẹ jawọ ẹ ma ṣe kanju jaiye, ẹ ma kanju labẹgbona, ẹ ma kanju ju asiko ọlọrun lọ, ẹ lọ ni suru, ẹ fi awọn ọkunrin lọrun silẹ, Ẹnyin ti o jẹ pe wọn ran lọ si ile ẹkọ ti o jẹ pe ẹ ko lọ tabi ti o nlọ ti o ko ki ka iwe rẹ nile ti o ya Olodo, iwọ ni mo nba wi, o ko mọ ju pe ki o tele ọkunrin lọ, tabi ki o lọ ra aṣọ asiko, iwọ lo mọ Bonfo tabi Rapa, Ọmọ ti ko to ẹ nka iwe kejọ, Alakọri rẹ nka iwe mẹta, inu rẹ si dun, o ko mọ ju pe ki o ma gba owo lọwọ ọkunrin lọ, Iwọ kan na ni o fẹ Burọda Onimọto ti o si gba owo lọwọ rẹ, bakanna ni o si tun gbowo lọwọ Burọda Ẹleran, bẹ na ni o si tun fẹ Fatayi ti o si gbowo lọwọ rẹ lati iwo yi ẹ lọ. Bẹni ile ẹkọ ni wọn ran ọ, o bọ wa dun ọ ni igbẹhin bẹni Obi rẹ nja ki o le kawe mẹwa, Alakọri rẹ ko rori nitori rẹ. O di ọwun fun ọ.

Awọn Obi nyin nsare kiri nitori owo ile iwe, wọn ko mọ pe ọkunrin lẹ nba kiri ti ẹ gbowo lọwọ wọn. Emi ko tilẹ mọ ohun ti ẹ fi owo na ṣe, nigbati o jẹ pe awọn Obi yin nfi gbogbo nkan tẹ yin lọrun, eb iko pa yin, orugbẹ ko gbe yin, ẹ ri owo na, ẹ ri aṣọ lo, kini otu ku? Kilo fa ti ẹ tun lọ gbowo lọwọ Ọkunrin, ṣe iranti pe bi awọn Obi ko ba ri yin Ẹlẹda wọn ri yin ẹlẹda na ni yio ma dajọ fun yin ti wọn ko le sun nitori tiyin wọn fẹ ki igbesi aiye yin dara. Ṣugbọn ẹnyin ṣoṣi bi ẹran aṣẹwo, eyiti ẹ ko ba fi joko kawe yin, ile Ọkunrin lẹ nlọ, ti iwo yi gbe igba osi dani, iwọ ko ri obinrin ẹgbẹ rẹ tio di "SENIOR SERVICE" ko ṣe pe bi iwọ ṣe ṣe ni awọn na ṣe ni, njẹ wọn le de iru ipo ti wọn wa loni yi, ko si iṣẹ ti ọkunrin le ṣe ti Obinrin ko le ṣẹ o wa lọwọ bi ẹ ba ti mura si ẹkọ yin, iwọ ti o si gbe ọkan le ọkunrin pe yio fun ọ ni owo, o ko mọ pe oṣi ni o fi sere, bi a ba wi wa lọ ko si Kaba, o ro bi ẹniti ko mọ iwe a mi wọ Kaba bi? gbogbo ẹwu Ọmọwe ni o wu ẹ wọ. iwọ ni o ko si fi oju siwe yi. Ti o ba ni iṣẹ lọwọ ti o mọ iwe rẹ dada Ọkunrin kan ko ni le ṣe fari si ọ.

Nitorina mo bẹ yin pupọ, ki ẹ jọwọ ki ẹ ronu piwada ki ẹ mura si we yin. Ogun yin ni awọn Obi yio pin fun yin yẹn, e ye tẹle awọn Ọkunrin mọ, ẹ ye lọ si ode ni ọjọ isinmi mọ, ẹ ma joko kawe yin nile, ẹ fi oju siwe yin ẹ ma ṣe kanju jaiye. Awọn ọmọ miran ti wọn ba ni awọn lọ sile ẹkọ wọn yio mu aṣọ kan dani wọn yio fi si isalẹ apo wọn ti wọn ba kuro nile tan, wọn yio wa bọ ẹwu ile iwe silẹ, wọn yio wa wọ eyiti wọn mu dani, wọn ama rin kakiri ile taja bi Kingsway tabi ile awọn ọkunrin mo bẹ ẹnyin ti ẹ nwu irufẹ iwa bayi ki ẹ lọ fi silẹ, ko dara igbesi aiye yin lẹ bajẹ ti ẹ ko mọ, Ẹnyin ti ẹ ri enia ran yin lọ ti ẹ ko si lọ ti ẹ ko mọ ju pe ki ẹ ma tele ọkunrin ọmọ jaiye lọ, Aṣiri yin nbọ wa tu, o jẹ tete lọ jawọ ninu rẹ ki ẹ mura si ẹkọ yin nisiyi, ki o to di pe o ko ni le kọ mọ. Ẹnyin Ọdọmọbinrin ẹ ye gbowo lọwọ ọkurnin, mọ, ẹ ṣe anu awọn Obi yin ti wọn pa ebi mọ nu nitori owo ile iwe yin. Ẹnyin ẹ tilẹ ronu yin wo pe Obi ti o na wo le wa lori yi, owo na ko ma le pada si ọwọ wọn mọ, wọn fẹ ki igbesi aiye wa dara ni, ẹ gbọrọ si awọn Obi yin lẹnu, pupọ ninu awọn ọmọdebinrin isiyin ni wọn a jaju mo Obi tabi ki wọn ma kọṣẹ fun Obi wọn, iru iwa bayi ko dara, ẹ ma gbọrọ si awọn Obi yin lẹnu, ẹ ṣe iranti wahala wọn lori yin lati kekere, ẹ fi gbogbo iwa aibikita yi silẹ, ki ẹ si mura si ẹkọ yin.

IYOKU DI ỌSẸ TO NBỌ

ỌNA IRỌRUN KAN NIYI O.

ṢA SO FUN AWỌN TI O NTA IWE IROHIN FUN Ọ PE KI O MA JU IROHIN IMỌLẸ KAN SINU ILE RE NIGBOGBO ỌJỌ

## Monday. Ema ka iwe Irohin Imole losese, ki e si ma polowo Oja yin sinu re

**For all your Printing Requirements**

Invitations, Programmes, Hand bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

Where Quality Print, costs less.



# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

### ENIA META GBA IDAJỌ ẸWỌN ỌDUN MARUN

YABA:— Laipẹ yi ni ile ẹjọ giga ti Y a b a fi awọn ọdaran kan si Ẹwọn ọdun marun ati osu mesan nigbati nwọn jẹbi wipe, nwọn fọ Ile ti o wa ni ọna Ikorodu Yaba, ti nwọn si ji awọn D u k i a ti o to okole-irugba pọnun ati sile mesan gbe, eyiti o jẹ ohun ini awọn ẹgbẹ Erid Custodis ati Benard Herzong.

Nweke Namuoh, William West ati Lazarus Nwigue ni awọn ọdaran na, Nweke Nemuoh gba idajọ Ẹwọn osu mesan, William West ọdun mẹta ati Lazarus Nwigue ọdun mejì.

### FIFI PỌNUN MARUNDILOGOJI TANRAN FUN IWAKIWA TABI ẸWỌN

ENUGU:— Ọgbẹni awa m o t o kan ti oruko rẹ njẹ Uzodima Obiora ni ile ẹjọ (Magistrate Court) ti Enugu ni ki o fi Pọnun marundilogoji tanran tabi ki o lọ gbẹwa osu meji ni ọgba Ẹwọn fun iwakuwa ti o nwa moto rẹ, moto na kò tun ni iwe asẹ irinna ati iwe aṣẹ idabobo.

Ni ile ẹjọ kanna ni Ọgbẹni John Ngene ti gba idajọ osu mejidilogun ni ẹwọn fun pọnun marundilogoran ti o ji gbe lọdọ awọn Oniworobo ni ọja Onitsha.

### EYI ARA, ỌKỌ'YAWO KU LẸHIN WAKATI MẸJỌ TI NWỌN ṢE IGBEYAWO RẸ

ABEOKUTA:- Oloye Joa Obadeyi ti o nse isẹ Ilekiko (Contractor) ni Eko ni a gbọ wipe, oyi gbe lulẹ ti o si ku, nigbati o di wakati kẹjọ ti o se Igbeyawo rẹ tan.

Bi tọkọ-taya ti jọ nbọ lati ibiti, nwọn ti se Igbeyawo, nwọn dori kọ ile Iyawo, bi awọn mejeji ti fẹsẹ bọ ile ana ni Ọkọ Iyawo ba ṣubu lulẹ, nibi ti gbogbo awọn ọrẹ, ojulumọ ti o ti joko lati ṣe ẹyẹ ti Iyawo.

Oloye na fi Ọmọ metalelogun ati Iyawo mewa Saiye jo, ki Ọlọrun ma yọ wa ninu iru ewu ba wọnyi o Amin.

### ENIA MẸFA GBẸWA FUN ILỌNILỌWỌGBA

BORGU:- Awọn enia merin ninu awọn Osiẹ Ijọba Ibilẹ Borgu ati awọn ara abule m e j i, ni ile ẹjọ Ijọba Ilọrin ti sọ si ẹwọn ọdun kan titi de ọdun mẹta, nigbati nwọn jẹbi ẹsun pe, nwọn lọ Fulaini kan l ọ w ọ gba ohun ọsin rẹ. A w ọ n Ọgbẹni na ni M. Husseini, M. Bio Bussa Mogo, Papiri Audu Danderi ati Aliyu Aba.

### ẸSẸ MI O! ẸSẸ MI O! LO NKE BI O TI NKU LỌ

KANO:- Ọgbẹni Moses Ayọdele Ogundipẹ ẹniti o jẹ akọwe ti ntoju ibiti a nkẹru si (Storekeeper) ni Kano ni a gbọ wipe o ku ni oru alaruba nigbati o ti igbe bọ ẹnu wipe ẹsẹ mi o, ẹsẹ mi o, ni o ba mi kanlẹ, lo bu lọ jẹ pe Ọlọrun. Ni irọlẹ ọjọ ni a gbọ pe Ọgbẹni yi lọ wo ran, ere ijo ẹniti wọn ma yan gẹgẹbi O m i d a n Naijiria (Miss Nigeria) ni ile Ero (Hotel) kan ti o wa ni Kano. Ki ere ọjọ na to bẹrẹ ojo nla kan rọ eyi ti o fa ti wọn fi sọ ere na di ọjọ miran, ni ọkunrin yi ba pada wa si ile rẹ ti oju ile kẹjọ ni opopo S a n u s i (8, Sanusi Street). Gẹrẹ todi agogo mesan ni oba lọ sun bi o ti di iseju bi marun ti o lọ sun ni iyawo rẹ ba gbọ ariwo ti ọkọ rẹ nke, lo ba sare lọ ba ọkọ rẹ wipe ki lo nse to ke, kini o ṣẹlẹ si ẹsẹ rẹ, bale mi bi o ti fọwọ kan oti tutu lo ba sa ku. Wọn si ti ye Oku rẹ wo lati mọ nti o pa Ọkunrin na ni ile Onisegun.


I J A F A R A L E W U

## Ma tan Ara re je mo!

Bi o ba daju wipe "IKỌ" tabi amodi "IGBAAIYA", lo nyọ ọ lẹnu ti ọjọ rẹ si ti pẹ pupọ, ma tan Ara rẹ jẹ mọ nipa rira awọn "EGBOGI RỌBIRỌBI" ti nwọn nta kakiri Ode misinsinyi ni owo pọku. Wọn kò le se iwosan "IKO" ti ọjọ rẹ ti pẹ rara. Sọbu kan na ti o le ri orisirisi egbogi "IKO" ti o daju, alamatase, ati Ajẹbidan lati ilu awọn Jamani, Faranse, ati Itali (Tatabulu) ra ni Igboro Ilu Eko tabi ni sọbu awọn ara Ilu Saro ti nwọn npe ni:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos. Phone: 22875
NIGERIA (Ọja ita Faji)


# IDIJE IDIJE IDIJE

A fi eyi se Ikede fun gbogbo Ọkawe Irohin Imọlẹ Jake-Jado Agbaiye ati awọn Ọmọ Karo-o-jire pe anfẹ:- Ẹniti o ba le ba wa fi awọn ọrọ si ibiti a fa i l a kekere si, ati pe awọn kan tun wa ninu rẹ ti a ko to dadaanfẹ ẹniti o ba le ba wa to si ipo rẹ daradara ti yio si ni itumọ.

Enikẹni ti o ba si bori ninu gbogbo rẹ yio gba Ẹbun pọnun-kan sile-kan (£1 : 1/-).

### ỌRỌ NA NI WỌNYI

Ọrọ yi jẹ oruko awọn enia pataki nilẹ Yoruba ti nwọn si ti di ologbe:-

| | |
|---|---|
| 1. __ __ A __ Y __ __. | 6. M __ __ E __ __. |
| 2. O __ __ N __ __ | 7. __ A __ __ O. |
| 3. __ __ U __ __ W __ | 8. O ... O __ ... __ I. |
| 4. O __ __ P __ __ __. | 9. O __ __ N—O __ __. |
| 5. B __ __ __ __ __ —N. | 10. A ... ... T __ __ __ |

Oruko yi jẹ, oruko awọn Ọba nilẹ Yoruba

1. O __ __ N __ __
2. E ... __ J __ __ B ...
3. A __ __ W __
4. O __ __ D __
5. A __ __ __ __ U __ __

Tun awọn ọrọ wọnyi to dara-dara:-

1. GOOINANS __ __ __ __ __ __ __ __ __
2. AIJNIDE __ __ __ __ __ __ __
3. GABRNOI __ __ __ __ __ __ __
4. ASLIHE ... __ __ __ __ __
5. OINMMION __ ... ... __ __ __ ... __

Awọn orukọ wọnyi jẹ, orukọ Ilu ni ilẹ Naijiria:

1. ... G ... O __ __ __
2. I __ B ... __ A __ O.
3. K __ __ A __ C __ __ N
4. A __ __ T __ G __ O
5. __ A __ __ B __ R.

AKIYESI:— IDIJE yi yio pari ni gbigba ni ọjọ kẹta oṣu keje ọdun yi (3 : 7 : 61) kọ ọrọ tirẹ ki o han rekete, ẹniti tirẹ ko ba han, a o fa ya ni, ki ẹ si mọ d a j u wipe, ko si ojoro ninu Idije na, ẹniti o ba se gbogbo rẹ, ti o si gba a, ni a o fun ni Ẹbun pọnun-kan Ṣile-kan (£1 : 1/-) Postal order ranṣẹ si.

Fi Stamp Toro ranṣẹ fun gbigbe pọnun-kan Ṣile-kan ti o ba jọ ranṣẹ si ọ. Ge ibiti Idije yi gbe wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp Torọ tirẹ. Enikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ, ti ko ba si fi Stamp-Torọ ranṣẹ pẹlu, ti o ba jẹ a ko ni fi ranṣẹ si onitọhun, a ko si ni fun ni Stamp rẹ pada mọ

Orukọ ______________________

Ibugbe ______________________

______________________

Iṣẹ ______________________

Ọjọ Ori ______________________

Fi Idije tirẹ ranṣẹ si:—

OLOTU IROHIN IMOLE
16 BAMGBOSE STREET LAGOS

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

### ENIA MẸTA GBA IDAJỌ ẸWỌN ỌDUN MARUN

YABA:— Laipẹ yi ni ile ẹjọ giga ti Yaba fi awọn ọdaran kan si Ẹwọn ọdun marun ati osu mẹsan nigbati nwọn jẹbi wipe, nwọn fọ ile ti o wa ni ọna Ikorodu Yaba, ti nwọn si ji awọn Duka ti o to okole-irugba pọnun ati ṣile mẹsan gbe, eyiti o jẹ ohun ini awọn ẹgbẹ Erid Custodis ati Benard Herzong.

Nweke Namuoh, William West ati Lazarus Nwigue ni awọn ọdaran na, Nweke Nemuoh gba idajọ Ẹwọn osu mẹsan, William West ọdun mẹta ati Lazarus Nwigue ọdun meji.

### FIFI PỌNUN MARUNDILOGOJI TANRAN FUN IWAKIWA TABI ẸWỌN

ENUGU:— Ọgbẹni awa m o t o kan ti oruko re nje Uzodimma Obiora ni ile ẹjọ (Magistrate Court) ti Enugu ni ki o fi Pọnun marundilogoji tanan tabi ki o lọ gbewa oṣu meji ni ọgba Ẹwọn fun iwakuwa ti o nwa moto rẹ, moto na kọ tun ni iwe aṣẹ irinna ati iwe aṣẹ idabobo.

Ni ile ẹjọ kanna ni Ọgbẹni John Ngene ti gba idajọ osu mejidilogun ni ẹwọn fun pọnun marundilogoran ti o ji gbe lọdọ awọn Oniworobo ni ọja Onitsha.

### EYI ARA, ỌKỌ'YAWO KU LẸHIN WAKATI MẸJỌ TI NWỌN ṢE IGBEYAWO RẸ

ABẸOKUTA:- Oloye Joa Obadeyi ti o nṣe iṣẹ Ilekikọ (Contractor) ni Eko ni a gbọ wipe, oyi gbe lulẹ ti o si ku, nigbati o di wakati kejọ ti o ṣe Igbeyawo rẹ tan.

Bi tọkọ-taya ti jọ nbọ lati ibiti, nwọn ti ṣe Igbeyawo, nwọn dori kọ ile Iyawo, bi awọn mejeji ti fẹsẹ bọ ile ana ni Ọkọ Iyawo ba ṣubu lulẹ, nibi ti gbogbo awọn ọrẹ, ojulumọ ti o ti joko lati ṣe ẹyẹ ti Iyawo.

Oloye na fi Ọmọ metalelogun ati Iyawo mẹwa Saiye jọ, ki Ọlọrun ma yọ wa ninu iru ewu ba wọnyi o Amin.

### ENIA MẸFA GBEWA FUN ILỌNILỌWỌGBA

BORGU:- Awọn enia mẹrin ninu awọn Oṣiṣẹ Ijọba Ibilẹ Borgu ati awọn ara abule meji, ni ile ẹjọ Ijọba Ilọrin ti sọ si ẹwọn ọdun kan titi de ọdun mẹta, nigbati nwọn jẹbi ẹsun pe, nwọn lọ Fulaini kan lọwọ gba ohun ọsin rẹ. Awọn Ọgbẹni na ni M. Husseini, M. Bio Bussa Mogo, Papiri Audu Danderi ati Aliyu Aba.

### ẸSẸ MI O! ẸSẸ MI O! LO NKE BI O TI NKU LỌ

KANO:- Ọgbẹni Moses Ayọdele Ogundipẹ ẹniti o jẹ akọwe ti ntoju ibiti a nkẹru si (Storekeeper) ni Kano ni a gbọ wipe o ku ni oru alaruba nigbati o ti igbe bọ ẹnu wipe ẹsẹ mi o, ẹsẹ mi o, ni o ba mi kanlẹ, lo bu lọ jẹ pe Ọlọrun. Ni irọlẹ ọjọ ni a gbọ pe Ọgbẹni yi lọ wo ran, ore ijo ẹniti wọn ma yan gẹgẹbi Omidan Naijiria (Miss Nigeria) ni ile Ero (Hotel) kan ti o wa ni Kano. Ki ere ọjọ na lo bẹrẹ ojo nla kan rọ eyi ti o fa ti wọn fi sọ ere na di ọjọ miran, ni ọkunrin yi ba pada wa si ile rẹ ti oju ile kejọ ni opopo Sanusi (8, Sanusi Street). Gẹrẹ todi agogo mẹsan ni oba lọ sun bi o ti di iṣẹju bi marun ti o lọ sun ni iyawo rẹ ba gbọ ariwo ti ọkọ rẹ nke, lo ba sare lọ ba ọkọ rẹ wipe ki lo nṣe to ke, kini o ṣẹlẹ si ẹsẹ rẹ, bale mi bi o ti fọwọ kan oti tutu lo ba sa ku. Wọn si ti ye Oku rẹ wo lati mọ nti o pa Ọkunrin na ni ile Onisegun.

I J A F A R A L E W U

## Ma tan Ara re je mo!

Bi o ba daju wipe "IKỌ" tabi amodi "IGBAAIYA", lo nyọ ọ lẹnu ti ọjọ rẹ si ti pẹ pupọ, ma tan Ara rẹ jẹ mọ nipa rira awọn "EGBOGI RỌBIRỌBI" ti nwọn nta kakiri Ode msinsinyi ni owo pọku. Wọn kọ le ṣe iwọsan "IKO" ti ọjọ rẹ ti pẹ tara. Ṣọbu kan na ti o le ri oriṣiriṣi egbogi "IKO" ti o daju, alamatase, ati Ajẹbidan lati ilu awọn Jamani, Faranse, ati Itali (Tatabulu) ra ni Igboro Ilu Eko tabi ni ṣọbu awọn ara Ilu Saro ti nwọn npe ni:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos. Phone: 22875
NIGERIA (Ọja ita Faji)

# IDIJE IDIJE IDIJE

A fi eyi ṣe Ikede fun gbogbo Ọkawe Irohin Imọlẹ Jake-Jado Agbaiye ati awọn Ọmọ Karọ-o-jire pe anfẹ:- Ẹniti o ba le ba wa fi awọn ọrọ si ibiti a fa ila kekere si, ati pe awọn kan tun wa ninu rẹ ti a ko to dadaanfẹ ẹniti o ba le ba wa to si ipo rẹ daradara ti yio si ni itumọ.

Enikẹni ti o ba si bori ninu gbogbo rẹ yio gba Ẹbun pọnun-kan ṣile-kan (£1 : 1/-).

### ỌRỌ NA NI WỌNYI

Ọrọ yi jẹ oruko awọn enia pataki nilẹ Yoruba ti nwọn si ti di ologbe:-

| | |
|---|---|
| 1. __ __ A __ Y __ __. | 6. M __ __ E __ __. |
| 2. O __ __ N __ __ | 7. __ A __ __ O. |
| 3. __ __ U __ __ W __ | 8. O __ O __ ... __ I. |
| 4. O __ __ P __ __ __. | 9. O __ __ N—O __ __. |
| 5. B __ __ __ __ __ N. | 10. A ... ... T __ __ __ |

Oruko yi jẹ, oruko awọn Ọba nilẹ Yoruba

1. O __ __ N __ __
2. E ... __ J __ __ B ...
3. A __ __ W __
4. O __ __ D __
5. A __ __ __ __ U __ __

Tun awọn ọrọ wọnyi to dara-dara:-

1. GOOINANS __ __ __ __ __ __ __ __
2. AIJNIDE __ __ __ __ __ __ ...
3. GABRNOI __ __ __ __ __ __ __
4. ASLIHE ... __ __ __ __ __
5. OINMMION __ ... ... __ __ __ ... __

Awọn oruko wọnyi jẹ, oruko Ilu ni ilẹ Naijiria:

1. ... G __ O __ __ __
2. I __ B __ __ A __ O.
3. K __ __ A __ C __ __ N
4. A __ __ T __ G __ O
5. __ A __ __ B __ R.

AKIYESI:— IDIJE yi yio pari ni gbigba ni ọjọ kẹta oṣu keje ọdun yi (3 : 7 : 61) kọ ọrọ tirẹ ki o han rekete, ẹniti tirẹ ko ba han, a o fa ya ni, ki ẹ si mọ daju wipe, ko si ojoro ninu Idije na, ẹniti o ba ṣe gbogbo rẹ, ti o si gba a, ni a o fun ni Ẹbun pọnun-kan Ṣile-kan (£1 : 1/-) Postal order ranṣẹ si.

Fi Stamp Tọrọ ranṣẹ fun gbigbe pọnun-kan Ṣile-kan ti o ba jọ ranṣẹ si ọ. Ge ibiti Idije yi gbe wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp Tọrọ tirẹ. Enikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ, ti ko ba si fi Stamp Tọrọ ranṣẹ pẹlu, ti o ba jẹ a ko ni fi ranṣẹ si onitọhun, a ko si ni fun ni Stamp rẹ pada mọ

Orukọ ______________________

Ibugbe ______________________

______________________

Iṣẹ ______________________

Ọjọ Ori ______________________

Fi Idije tire ranṣẹ si:—

OLOTU IROHIN IMOLE
16 BAMGBOSE STREET LAGOS